# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. NO. 30. SATURDAY, FEBRUARY 3, 1923. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### EYI ṢE KELEBỌ!!!

Ọrẹ wa k[illegible] ti ẹṣin rẹ wo ni iwọn ọsẹ to kọja ni lati san ponwun meji (£2) s'[illegible] awọn Munisipa fun gbigbe ati sisin oku ẹṣin na, ni ọna-jijin ni Ik[illegible] a ko mọ, bẹ si ni ọpọlọpọ enia ko mọ pe irufẹ ofin bayi wa fun awọn ẹlẹṣin: ni igba lailai, ti ẹṣin ba wo bayi, awọn "ara oke" ti a ma nfun ni oku rẹ ti nwọn fi "nla'nu." Nigbati a wadi ofin titun yi, a so fun ni pe gẹgẹ bi Ijọba ti ro pe awọn apa kan oku ẹṣin bi emi ni ida-ngborogbo tabi ori rẹ ti a ju sarin ita ti eṣinṣin ma ngbaru yĩn, nma ntan arun kakiri ilu, nitorina ni a ṣe fi opin si gbigbe oku ẹṣin fun awọn ti nwọn mọ̃ fi se "Kọtọ" ọbẹ, ti oku na si di sinsin bi oku enia.

### ILE ẸJỌ, ẸRU JẸJẸ.

Comina Agba lọ bẹ Ọgba Ọlọpa'wo ni Ita Tinubu ni *Monday* ọse yi nipati fifẹ ti Ijọba npete ati fẹ "Ọja-Ọba" (Kotu) ti o nkun akunya nisisiyi.

### KILẸ NṢE T'Ẹ PỌ TO YI? IYAWO L'A NGBE O!

Ọgbẹni ISAAC THOMAS ti ibi-iṣẹ Munisipa yio gbe Omidan KOLA SMITH niyawo ni ọjọ *Thursday* ọsẹ to mbọ ni Ṣọṣi-Ọlọpẹ (Arọloya) ni agogo mẹwa-abọ larọ. Ki Baba m'ọjọ ro:

## ELEGBO TURUKU, A-F'OMI-EGBO J'IYAN L'EREKO.

Orin ti awọn ọmọde ma nkọ fun awọn ẹgbẹ wọn ti nwọn ngbe egbo wọn lọ si Ile-elegbo l'Ereko, ni igbani ni a kọ yi, eyi si mu wa ranti ohun ti a ka ninu Iwe-irohin Ijọba ti ọjọ 25 oṣu to kọja pe Ijọba fi aṣẹ si pe ki ẹnikẹni ti ki ba ṣe akuṣẹ, ma sanwo ti oluwa-rẹ ba lọ tọju ara rẹ ni gbogbo "Ile-elegbo" ti Ijọba ni ọna yi.

Fun a-kọkọ lọ, lati sisì (6d.) de ṣile kan abọ Fun lilọ sibẹ lẹhinna, lati kọbọ kọ-kan de sisì (6d.)

A si sọ pe awọn "Dokita" ti yio wa lẹnu iṣẹ ni Ile-elegbo bayi ni a fi le lọwọ lati mọ bi ẹnikan ni'pa ati sanwo t'a wi yi, tabi bẹkọ.

## IGI-IKATE NFORI GBUSI LASAN IKU TO NPẸJA WA NI 'SALẸ OMI.

A ni lati sọ pe ọrọ ti a gbọ nipa ti Ẹni-ọwọ J. A. LEIGH ti a sọ nipa rẹ lọsẹ to kọja ko ti ẹnu *member* ki *member* Ṣọṣi na de ọdọ wa, gẹgẹbi ọrẹ wa "Ẹni-Ọla" to kọwe sinu Iwe-irohin yi lọsẹ yi ti ro. Ibomiran ni ibọn ndun patapata.

## K'Ẹ TO R'ỌBA, AFI B'Ẹ RI KỌTUN O!

A ṣọpẹ lọwọ Ọgbẹni KARIMU KOTUN fun Iwe-ika-ọjọ-oṣu ti ọdunni to fi ta wa lọrẹ ni lọlọyi; kosi-botiri ni Iwe na, Ẹnikeji!

## ẸNI-ỌWỌ ONITIJU.

Bẹ si ni a dupẹ lọwọ Ẹni-ọwọ J. A. LAKERU fun Iwe-owe kan to ṣẹṣẹ ṣe to fi bun wa laipẹ. A nta Iwe na ni Ṣabu awọn C.M.S. Ṣile kan pere ni.

## T'OWO-LAWI.

Ijọba npete a ti ya lile ni ẹdẹgbẹta ọkẹ ponwun (*over £10,000,000*) fun orisirisi Iṣẹ-ilu, gẹgẹbi a ti ri ka niun Iwe-irohin Ijọba ti ọjọ 25 oṣu to kọja.

## AJẸ NKE OKUNRUN KO PARAD... O LOWO ẸBỌ NILE?

Ile-ẹjọ awọn *Jury* ṣi ni ọtunla (*Monday*) a ni awọn ara wa ti a ti fi Iwe pe si Iṣẹ n... niran ki nwọn ma gbagbe ati tete de ib... bibẹkọ, afara pọnwun mẹdọgbọn nja wọn!

## ỌKUTỌ, ỌMỌ OṢAREWA ṢAKIN, ỌMỌ AFINJU ỌLỌJA T'O S'ỌYỌ RỌ...

Inu wa dun lati gbọ pe Ọgbẹni Andre... Ọlatunji Thomas ọmọ Saraki wa Ọgb... A. W. Thomas Onile-nla-ti-mb'ole-lẹ... ti Anikantamọ ti wọ Igbalẹ (*has enter... the Inner Temple*) lati kọ iṣẹ Lọya ni ibi-iṣ... Ọba (*London*) ati pe o nṣe bẹbẹ ninu iyti... rẹ. A yẹ ẹ o, ọmọ Ọnaṣokun!

## O DI GBERE!

A ba awọn ẹbi Ọgbẹni Samuel ... Roberts ti ita Rief ni agbegbe ita Marti... kẹdun iku Ọgbẹni na to ṣẹlẹ ni ọjọ *Monda...* ọsẹ yi.

## IDARAYA AWỌN ỌMỌDE.

A fẹ ki ogoji awọn ọmọde l'ọkunr... l'obinrin ja alọ ti a tẹ sinu Iwe-irohin yi. nw... ni lati fi iwe ti nwọn ba ja si, ṣọwọ si wa titi ọsẹ mbọ: ki nwọn kọwe si oju-iwe kokan, ki ẹ... kokan ti o sure Ije yi fi tọrọtọrọ (3d.) ṣọwọ p... iwe rẹ.

Ao fi ẹbun mẹta fun awọn to ba ṣe rere ni alọ wọnyi :—

| | |
|---|---|
| Ẹbun kini | 5s. |
| „ keji | 2s. |
| „ kẹta | 1s. |

A o tẹ orukọ awọn to ba jagun-molu na, ati gbọ... jija awọn alọ na sinu Iwe-irohin yi.

Ki ẹ fi esi ṣọwọ si
"Arapa-sọwu"
c/o Editor "Eko Akete" Eko.

1. Araba baba mi lailai, araba baba mi lailai, ki iti ori gun u, bẹni a ki iti idi gun u.
2. Aṣọ baba mi lailai, aṣọ baba mi lailai, bi... ba kan ilẹ iṣe ni ifaya.
3. Nwọn ni ngbe e wa, mo gbe e wa, nwọn... ngbe pada mo ṣe e ti.

4. Onikun ringindin ṣubu, ipakọ rẹ tu ọyun pu ẹ.

5. Aṣa gbigbẹ tiẹtiẹ, o ba le ori igi gbigbẹ tiẹ tiẹ o njo mati-aga-tenge, mati-aga-tenge.

6. Ojiji fi i ẹranko a firu madoje.

7. Ko ni oju, ko ni imu, ọti oyinbo kun inu rẹ tẹtẹ.

8. Iya ku a gbe ọmọ sin.

9. O fin winni-winni majalalo, ọ pọ ṣọrọ majalalo ọ gba tii ti i majala lo; mẹta la pa a, mẹta ja a.

10. Oruku tindi-tindi, oruku tindi-tindi, oruku ẹ si ọna ki, o ni ki nwọn ma ṣa ina ori on jẹ.

11. Ọmọ baba mi lailai, ọmọ baba mi lailai, o kẹre titi, o pọ titi, iṣe ni ifi ẹpoti ti ẹsẹ ki o to ka ẹtemfe.

12. Nana kukuru mọ ọti pọn, ko mọ ọ ta.

---

## AIYE LABẸGAN.

i Editor "Eko Akete"

...agba,—Ko ya ni lẹnu rara lati ri irufẹ iwe ti ...banilorukọjẹ kan kọ sinu iwe irohin ọsẹ to kọja, ...ẹni ẹniti Ọlọrun ko bajẹ o ṣoro ki enia to le ...a a jẹ; nigbati a sọ nipa ọrọ ti a ko mọdi rẹ daradara si Alufa J. A. Leigh, ti Ijọ Jordan, Oke Suna. Eyiti a wadi rẹ finnifinni ti a si ri wipe ...ọ ko ri bi a ti sọ sinu iwe irohin na. "Ọta ni ... ṣe eyi." Ọrọ ti Alufa na dabi itan Joseph ni ile Potiphar nigbati o sọ wipe "Emi yio ṣe ṣe ...uburu yi ki nsi dẹṣẹ si Oluwa." Ati bi itan ...luwa wa pẹlu Judas, eyiti o wipe, "Ẹniti nba ... i jẹun pọ ti gbe gigisẹ rẹ si mi." Bi a ba ni ..., ọmọran a mọ, owe na ti ẹniti o jẹ mọ. Baba ... Alufa R. A. Coker, aṣe, o ni ohun ti agba jẹ ...lẹ ikun ki o to pe iya yo on, toto o. Aṣe, o nidi ...gbati o gun ori *Pulpit* Jordan ti o si nfi awọn ...ṣi enia bi melo kan joye nijọ kini, ti o fi ẹlomi ...ye Judas, aṣe, orukọ a ma ro enia? Awọn ...warẹ koi ye hu iwa Judas na di oni yi o; adura iru awọn ẹni bẹ ni pe ki Oluwa ma ṣai ji ohun ...kan wọn, ki akoko to to "Ẹhin kule lọta ... ile ni aṣeni ngbe." "Bi iku ile ko pa ni tọde ... le ri ni gbe ṣe." Oluwa ko ma ṣai gba ni lọwọ iru awọn ẹni bẹ o. Nṣe ni a ṣebi oju Ijọ Jordan ... fa jubẹlọ, lẹhin iwe ẹsun ti nwọn ti kọ nipa alufa R. A. Coker si awon olori, eyiti o mu ki ... fa na fi ibinu fi iṣẹ silẹ, biotilẹjẹpe o dagba, ... iṣẹ ko su u ṣe nigbana. "Eyi ara," Ijọ wo ... ẹnyin ti iri ti o kọ iwe ẹsun gbọrọgbọro lati ... wọn sun, bi o ti wu ki ede aiyede da wọn pọ to, nwọn a fi ifẹ yanju rẹ larin ara wọn. Ẹnyin Ijọ Jordan, ẹ dẹhin lẹhin abanilorijẹ ti o nkọ yin ...ikọkukọ, ti o si nti ọwọ yin bọ ṣọlọ. Tani ko mọ ninu iṣẹ ti Ọba ni, tabi ninu iṣẹ iwasu ti o nawọ le ni kutukut arọ rẹ, ki o to ṣubu logedengbe bi Lucifer ti ko le dide mọ. Nigbati o mọ wipe iṣẹ na ka en lara tobẹ, ko ṣe fi ẹsẹ mejeji mulẹ daradara, ki o to yọ lulẹ. Ẹ lọ simi lẹhin ọmọ Eli, ti o nlu agbanṣina fun nyin jo. "Ẹ ti ṣẹṣẹrẹ bọ agbo, ki ẹ wi fun alejo ko lọ." Bi o ba ti yọ lorere ọkankan Ṣọṣi Jordan ni o ti ma wọ ẹwa apakan iṣẹ ti Ọlọrun fifun Alufa Leigh ṣe ni Jordan bi o ti nwẹ ode ara Ṣọṣi bẹni o nwẹ inu rẹ ki iwamimọ le fi ara han nipa agbara Ọlọrun fun iyin ati ogo orukọ Rẹ. Mọmọ mọ pe lati ibẹrẹ ni ni Ṣọṣi Bẹrẹfutu ti jẹ Iya fun Ṣọṣi Jordan, eyi ki iṣe ohun titun labẹ ọrun. Bi o ba si yẹ loju Oluwa, bi ọmọ ba to ni apo, a ni apo. O dẹ ti to akoko nitori awọn miran ti o dide lẹhin rẹ ti dado funra wọn. A si jẹ ayọ ọpọlọpọ enia lati ri pe o ri bẹ laipẹ yi, a fi le nyin lọwọ o, Ọba alaṣẹ ekeji oriṣa. Wipe Alufa na ko gbọdọ da owo kan na, tabi ki o da ṣe iṣẹ miran ti o jẹ mọ Ṣọṣi na jẹ ogbologbo irọ tabi eke. Bi ẹniti o fi ọrọ na sinu iwe-irohin na ba si mọ pe ogun on da on loju, ki o fi ran ori nipa didarukọ ara rẹ. Alufa Leigh, ẹniti a nbuku ti Ọlọrun nbukun. Malu ti ko ni iru Ọlọrun yio ma le eṣin fun ọ ninu iṣẹ rẹ, maṣe bojuwo ẹhin, sa ma ba iṣẹ lọ. Oluwa na ẹniti o nsin, yi o ma ṣe atilẹhin fun ọ o. Ki Woli mi maṣe bẹru, bi Griki ati Ju nkẹgan. "Bẹni nwọn sa ti nṣe si awọn woli ti wọn ti mbẹ ṣaju nyin."

Emi ni tirẹ nitotọ,

ẸNI-ỌLỌLA.

---

Ọgbẹni oniwe-irohin "Eko Akete"

Ọgbẹni mi ọwọn,

Gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ lati sọ ọrọ gbolohun kan tabi meji fun ọgbẹni wa T. B. Bukọ, igbakeji akọwe agba ni ile ẹjọ nipa ofin titun to da silẹ ni ijọ kẹsan oṣu yi nigbati a bẹrẹ ẹjọ ganran eyi ti awọn agbagba mẹta ma nṣe aṣaro le lori.

Ofin yi ni pe, akọwe Lọya kan ko gbọdọ joko ni ibujoko wọn a fi ti wọn ba pe ẹjọ Lọya rẹ; ofin yi dara pupọ, ṣugbọn ọgbẹni wa yi gbagbe wipe, ki ṣe akọwe Lọya lani lati pa iru aṣẹ yi fun pẹlu ọwọ lile ti ọgbẹni wa yi mu, ekini, Lọya miran a gbe ẹjọ rẹ fun ẹnikeji ko ba on ṣe e, a si ran akọwe rẹ lati lọ feti si nkan ti adajọ ba wi ẹlomiran lati kọ gbogbo nkan to ba ṣẹlẹ silẹ ninu iwe. Nigbati a bere idi irufẹ ofin yi lọwọ ọgbẹni wa yi, o ni nitoripe awọn Lọya to ti Calabar pọ, ki nwọn ba le ri aye joko.

Ọrọ Ọgbẹni wa yi, dara pupọ, ṣugbọn nigbati awọn Lọya Calabar lọ tan nkọ, ọgbẹni yi wa fẹ fi aṣẹ rẹ mulẹ pẹlu ipa, ṣugbọn o gbagbe wipe "Iyi ni Ọba nfi ori bibẹ ṣe Ọba ki mu ẹjẹ." Ọpọlọpọ ninu awọn akọwe yi, wọn ṣe ẹsọ ati ifoju ara wọn tobẹ gẹ ti a fẹ le ma mọ iyato larin awọn ati ọga wọn, ṣugbọn ẹpọlọpẹ akọwe Lọya miran ti ni loju pupọ ọ.

Nitorina abẹ Ọgbẹni wa yi nipa ofin rẹ yi ko mu u kuro motipe iye awọn to nma joko ninu awọn akọwe yi nwọn ko wa ṣere a si tun kilọ fun ẹnyin ẹlẹgbẹ wa bi ọga nyin ko ba wa si ile ẹjọ ẹ ma wa ṣe oraye ẹru to nsa ti wọn ba ran yin wa fun ẹjọ kan ẹ bere lọwọ akọwe kotu, nitori nkan to mu mi ko iru iwe bayi o jẹ nkan idojuti pupọ, lati ti wipe ọkan ninu wa a joko, akọwe kotu a gbe e dide pẹlu idojuti.

Pataki ohun ti mo fẹ sọ fun nyin nipe ki ẹnyin t' ẹ ba pe ara nyin ni akọwe Lọya ki ẹ mura niwọntunwọnsi, nipa eyi bi ọga yi ko ba tilẹ fẹ fun nyin lowo si owo nyin, to ba nri bi ẹ ti nmura, a fun nyin kun u.

Ẹyin ọga wa Lọya "bi a ba nbu ẹtu ori a ma ro awo" bi akọwe kotu ba dojuti akọwe nyin abuku nyin ni, ki o ma mu irufẹ eyi wa wipe a ko mọ akọwe yatọ si iranṣẹ ninu awọn miran to ma nba Lọya wa si kotu.

Ọgbẹni T. B. Bakọ aṣẹ kaṣẹ ti ẹ ba ma pa ẹ jọwọ kẹ lẹ iwe rẹ mọ igi to wa ni Kotu ki a le tẹle e nitori pe nigbati o ba paṣẹ ti a ba ru aṣẹ na a di itiju, "ẹtẹ awo ni ẹtẹ ọgberi."

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Ọgbẹni Oniwe yi fun aye diẹ to fun mi.

Emi ni tirẹ nitotọ,
AKỌWE LỌYA.

---

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY FEBRUARY 3, 1923.

---

## AIYE IJỌUN KO JỌ TI SẸYIN, OṢUMARE, BỌ SIBI T'O WUN Ẹ K'O TA.

Ijowu ti a nri lọtun-losi lati iwọn ọdun melo sẹhin titi di oni larin wa nipa fifi orin ilẹ wa ati ilu bi Batakoto sin ni diẹ ni Ile-isin ti Ijọ enia Ọlọrun nibi ko le ṣe ko ma mu iṣiri wa fun olukuluku olufẹ nkan ilu rẹ. Nigbati a nri awọn Ijọ ti nwọn dawọ le ọna to tọ "suna" bayi o mu wa ranti iwasu iyebiye ti Igi-iwe ni, Dr. Mọjọla-Agbebi, (Ọrun-rere) ṣe nigbati awọn Ijọ BETHEL nṣe Ayadun wọn ikinni "Mọlẹ" yi ṣe Akanṣe Iwasu na ni alẹ ọjọ 21 oṣu *December*, ni ọdun 1902, ninu rẹ, o sọ "Asọtẹlẹ" pe Dundun wa, Batakoto wa, Gese wa, Kẹrikẹri wa. ati Samba wa jẹ ohun to yẹ ki a ma lo ninu isin-Ọlọruu ti a ba fi wọn si ọna to yẹ to si tọ: ko si ẹniti ko mọ pe ọrọ-asọtẹlẹ yi nṣẹ lọpọlọpọ aiye isinsinyi ninu awọn Ṣọṣi wa ti nwọ lo nkan wọnyi tobẹ ti okiki awọn Ile-isin na fi nkàn kakiri fun iṣẹ-iyipada ribiribi ti a nti ọna yi ṣe. Ohun to tilẹ tun jẹ ayọ ati inu didun fun wa ni pe ninu awọn enia wa ti nwọn wa ninu Ijọ okèrè bi ti C.M.S., ti *Wesley* ati ti *Baptist* njẹri si ẹtọ ati ẹyẹ t wa ninu fifi orin ni ohun ilẹ wa sin Oluwa a ko tanma pe nkan bayi le jẹ àbá enikẹni le pẹkẹlu ni iwọn ọdun mẹwa sẹhin nitori o jẹ aṣa awọn kan ninu wa lati m bu àtẹ lu ohunkohun to ba ti jẹ ti oril ede wa, ki nwọn si ma "gbe la-nkẹ" a oyinbo iba-dara iba-mada. Ṣugbọn ṣọpẹ pe a nri iyipada pupọ to tọ to si w ni lori nisisiyi: ohun to ku gẹgẹ bi ẹnika to kọwe sinu Iwe-irohin yi ni akoko ka ti sọ, ohun na ni pe ki ẹsọ ati mẹlọmẹ to wa nipa kikọ awọn orin wọnyi silẹ (*Native Composition*) ki a ma sọ iṣẹ na Oluwa mbu si yi, di "Ode d'ode ẹni" kàk bẹ, ki a tubọ ṣe "ko kari" ati jẹ ki gbogbo orin ilẹ wa ti a nkọ ninu Isin nisisiyi jọlọ ni kikọ silẹ ati ni kikọ ni orin: igbagbọ wa ni pe lọna yi, ni a le gba lati ma tubọ mu awọn enia wa wa sinu Agbo Kristi, ti Ihin-rere yio si le ma tan kakiri nibi ati ni ilu oke: eyiyi yio jẹ igberaga fun wa pe gẹgẹ bi a ti le fi orin sin lọna ti Oyinbo, bẹ gẹgẹ si ni a tun le fi orin sin lọna tiw bakanna ti ko pada !!!

Ajulọ ko pin sọdọ ẹnikan.

---

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O

OWO IRANLOWO TI A ṢI RI GBA ... WOṢOL.

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | 8 | |
| Owo ti a ti ri gba | 11 | 16 | |
| Dr. Moses Da Rocha | 1 | 1 | 0 |
| ... | £12 | 17 | 9 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ... ko rẹ nyin.

A o ma jihin ... ẹ.—[ED.—E. A.]

## MAṢINI TO NKẸ RIRI !!!

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,

Jamani Onişowo ara Hamburg, ṣẹṣẹ ṣi awọn ojulowo Ẹrọ-Iranṣọ ti Ọlọwọ ti a npe ni "MỤNDLOS" niIle-Ọja rẹ ni No. 7, Ita Labinjọ leti Ita Williams l'Eko.

Awọn Maṣini wọnyi wa fun kiko giri ni owo pọ ọ.

Awọn Maṣini Mundlos wọnyi jẹ eyiti a ti npe n "*Original Victoria*" ri, nwọn si ko ẹra kan ninu awọn Ẹrọ-Iranṣọ ti nwọn dara jọjọ: Nwọn ko kẹrẹ ninu awọn Maṣini atata ti ilu Jamani.

A o si fun ẹnikẹni to ba ra ninu wọn ni awọn eroja wọn wọnyi, awọn nkan bi,

*Hemming foot, Feller, Braider* ati *Trimmer*, awọn bi *Seamer, Ribbon binder, Quiler, Ruffler* ati *ribbon fastener*.

Ti iwọ ko ba le wa, kọwe ranṣẹ si Apoti-Ipin we wọn ni Ile Ipinwe, No. 459 l'Eko. A o si fi Iwe Aworan Maṣini na ṣowo si ọ.

Ẹ tete ranṣẹ, bi bẹkọ, Ẹran nyin yio bi Obukọ

---

## FOR SALE.

One Royal "Enfield" Motor Cycle, L. 690.
In good and working condition.

**For Particulars**

Apply to Mr. S. A. CLAY, 1, Macaulay Street,
Or at 75, Ọdunfa Street, Lagos.


---

We congratulate the Editor of our popular contemporary "Eko Akete" on his fight for the proper recognition of African Herbal Medicines; there can be little doubt that many of these specifics are more efficacious than the medicines prescribed by qualified medical practitioners, and in particular most of the patient medicine rubbish sold by traders. The British Pharmacopœia contains a very large number of drugs which Doctors have found in use by primitive untutored people in various parts of the world. Superstition plays no part in their virtues. And it can be said without fear of contradiction that Africans possess secrete remedies anodynes of precious valoe to life. It would abundantly repay professional men to study some of these herbal medicines for they represent, commercially, tremendous possibilities.

*The Voice of the People 13/1/23.*


WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON
Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ dẹ fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na ṣi "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## IROHIN ṢIṢI ILE-ISIN ỌLỌRUN NI ILU AWẸ (BATIST.)

A kuro ni Eko ni ijọ kejilelogun oṣu *December 1922*, lati lọ si Ile-isin Ọlọrun titun ni Awẹ lõjọ kanna ni a de Awẹ ni ago kan loru ni ijọ *Saturday* a ki wọn kakiri ni ọjọ *Sunday* ijọ kẹrinlelogun Ọgbẹni Isaac Adekunle Adejumọbi ti o ṣẹṣẹ jade ni ile iwe giga ti Baptist ni Ogbomọṣọ lo ṣe iwasu lõrọ ninu ihin-rere *Mait. 1 21.* Jesu ni iwọ o pe orukọ rẹ irohin ko to bi ko wa feti rẹ gbọ gẹgẹ bi o ti nṣi i lawẹ-lawẹ lẹhin na ni aṣalẹ a fun wọn ni ọrọ iyanju diẹ tabi iṣiri fun iṣẹ nlanla ti nwọn ti gbe kalẹ. Ni ijọ *Monday*, keresimesi ọdun de. Ni ago mẹwa arọ ẹse gbogbo ti pe si oju ọna ile titun lẹhin ti agogo da tan gbogbo wa jumọ kọrin yida ile na lẹhin na ẹni-ọwọ J. A. Babalọla ka *Psalm 100*, nigbati o ka a tan Ojiṣẹ Ọlọrun funfun J. C. Powell ṣi ilẹkun, gbogbo awọn ero rọ wọle kitikiti ati awọn ijoye—1. Ọyatolu, Balẹ Awẹ, 2. Adekomionsa Awẹ, 3. Ọmọtẹbẹ Jagun, 4. Adebiyi Arẹ-ago. 5. Aderin Otun Balogun, 6. Aṣatomi Iyalọja, 7. Akinọla Batun, 8. Sulu Ọdọfun, 9. Alao Balogun 10. Juawo Ọga ala, 11. Adewoju Iya gbogbo ilọya ara awọn oloye ko da nwọn ni nwọn ko le wa; Seriki ati Base awọn igbimọ wa pẹlu ati awọn imale alufa Buraimoh igbakeji Lemọmu ati awọn diẹ wa woran lẹhinna ni awọn Gbajumọ gbogbo ti Ọyọ wa; Rev. & Mrs. S. A. Ṣodipẹ, Mr. & Mrs. E. S. Cole Resident Clerk Ọyọ ati Mr. V. K. Ladele, Mr. L. A. Ogundeji chief-clerk District Officer. Mr. S. Ọladoyin, Lagos Store's, Mr. S. B. Barber, G. B. Ollivant, Mr. D. A. Adesọji, P. Z. & Co. ati Mr. E. B. Amọdu, Mr. S. M. Oyewọle court-clerk, Mr. J. A. Tẹla Public Works Department Mr. J. S. Adeniji, Motor Transport, Mr. Babalọla Ẹsan Mr. J. A. Durowoju, ati Mr. S. O. Ṣode ẹniti o fi agba *cement* kan ran wọn lọwọ ninu iṣẹ na, ṣugbọn ko le wa nigba ṣiṣi rẹ.

A bẹrẹ isin, a kọrin, ẹni-ọwọ A. Adeniji Puddicombe ka ninu ọrọ Ọlọrun *II Chro. 6: 18-42.* lẹhin orin ẹni-ọwọ funfun J. C. Powell sọrọ iṣiri lori iṣẹ ile na ati lilo rẹ lẹhin na a'fi iwe iyin fun awọn meji ti nwọn ṣe alabojuto iṣẹ na lati *October* 1920 titi di *December*, 1922 laigba owo kankan rara awọn ẹni-ọwọ J. C. Powell ati James O. Ogundipẹ fun iyọnu ati lala wọn titi iṣe na fi pari yi lẹhin na akọwe Ijọ, Ọgbẹni D. A. Ọlaọpa ka irohin owo ti nwon ti na sori ile na

Gbogbo owo ti wọn rigba.

| | £ | s | d. |
|---|---|---|---|
| Owo lati ọdọ ọmọ Awẹ l'Eko | 571 | 4 | 11 |
| Owo ti nwọn da ni Awẹ | 537 | 13 | 11½ |
| Ẹbun lati ọwọ awọn ọrẹ | 197 | 12 | 11 |
| Owo ti nwọn ya | 393 | 12 | 6 |
| Aropọ | £1,700 | 4 | 3½ |
| Gbese to ku lati san | 322 | 12 | 1 |
| | £2,022 | 16 | 4½ |

Owo awọn olukọ, ati ojiṣẹ lati

| | £ | s | d. |
|---|---|---|---|
| Oct., 1920 di Dec., 1922 | 356 | 13 | 6 |
| Owo ti nwọn fi ra Panu | 242 | 19 | 10 |
| Owo ti nwọn fi ra Iṣo | 9 | 8 | 9 |
| Owo ti nwọn fi ra Pako fun ile ati ijoko | 228 | 9 | 7½ |
| Owo ti nwọn fi ra Cement | 187 | 19 | 6 |
| Owo ti awọn oṣiṣẹ gbogbo | 448 | 1 | 10 |
| Owo nkan wẹwẹwẹ | 127 | 4 | 10 |
| Owo ti nwọn ti san ninu gbese | 93 | 12 | 6 |
| Owo iṣẹ eyiti gbogbo Ijọ ṣe laigba owo | 328 | 6 | 0 |
| Aropọ | £2,022 | 16 | 4½ |

Church na gun ni ọgọrun ẹsẹ, ibu rẹ jẹ ẹsẹ mejidiladọta. Ohun rere kan ha le ti Nasareti jade bi? jade ka lọ wo o. Jesu nṣe ohun ara larin ilu kekere na, gbogbo awọn to wa ni ọjọ iṣi ile na jẹ ẹgbẹdogun enia (3,000) o le diẹ; awọn ara na tọrọ adura nyin lori iṣẹ nlanla yi.


## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni

No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten.*)

Ati oriṣiriṣi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"


SOMETHING TO YOUR TASTE.

MR. J. D. ỌLAYAHA, Painting Contractor and General Decorator is prepared to undertaken all paint-works of every description to the entire satisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work: has worked for many important European Firms in town notably, the Firm of P. Z and also the local P. W. D.

Terms reasonable.
For particulars,
Apply at 16, Mọgaji Lane, Ẹpẹtẹdo.
A trial will convince you.

ỌMỌ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"
Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,
Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,
Ihin ko to afojuba
A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neuiasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

'Ajenifuja" Store
P. O.Box 201; 109

VIDAL. R. COLE
Broad Street Lagos

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onișowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

ni wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko
Ohun a jẹ lo mba ni lọ.


AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.


29, Oripasan Lane,
King's Quarter, Isale Eko,
Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plan Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc., Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vanish and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogaji,**
*General Manager.*


IGBẸ L' OWO WA.

Niger Company, African Eastern Co-operation MacIver & Co., gba Ekurọ ni £11 10 0. fun ton kan.

Pọwun mọkanlelogun £21 ni awọn oyinbo wọn yi gba Epo.

Cocoa £24 0. 0. to £25 0. 0. ni awọn oyinbo wọn yi ngba Cocoa pẹlu.


PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onișowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nṣe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi ṣile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi oriși-riși iwosan onirunru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku-yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati și ile Ẹrọ Idan Awoșẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Ṣoroko a gbe ṣeranwo ni igbati o ba și ibẹ
Irohin ko to afojuba.

***P.O.Box 159*** ***Phone 214***

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

( MORNING )

Masses Isin Aro,

6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

( EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 8 a.m.—Christ Church | Morning Prayer. |
| 10 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Rev. S. C. Phillips |
| 11 a.m.— do. | Ordination Service Bishop I. Oluwọle D.D. |
| 6.30 p.m. do | Rev: I. Kuti |
| 8. a.m. | |
| 8 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) do | Morning Prayer |
| 8 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | |
| 9 a.m....St. David's (Jordan) | |

**WESLEYAN**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. F. Platt |
| 7 p.m. | Rev. O. Dada |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. N. A. B. John |
| 7 p.m. | Rev. D. L. Mọjọla |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | |
| 7 p.m. | |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | |
| 7 p.m. | |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m | Bro J. T. A. White |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. E. A. Akiọla |
| 6.30 p.m. | Rev. Ebenezer Bresi-Ando |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Rev. N J. D. Shomuji |
| 4.30 p.m. | Bro. H. A. Williams |
| 9 a.m.—Ararọmi ( Baptist ) | Rev. A. A. Puddiconbe |
| 4 p.m. | Bro. J. Adekọya |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. F. Oshodi |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. D. Adesanya |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m.—Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ ( Bamgboṣe Street. )

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rt. Rev. F. Melville Jones

---


## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni "MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai ( Custom Street ) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan ; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

## Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o şi "Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọṣẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,

Ogun rẹ jire.

---

## "VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 12 Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBE.

*General Trader.*

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta oriṣiriṣi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---


N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAṢINI-ARANṢO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu enikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAṢINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣiriṣi Ilẹkẹ alarabara, Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipon, ati ẹja Abọmafọ ati oriṣiriṣi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi ṣi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AṢIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.


---


## Mogbe tana danu Mogbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Iṣẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun oriṣiriṣi awọn Egbogi wọnyi ti o ṣẹṣẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọṣẹ rẹ, Egbogi Iṣaka, Jẹdijẹdi, Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kiniṣa, Egbogi Inu riru iwaṣu, ati fun ọkunrin pẹlu, egbogi ki ara ọkunrin le giri (ko ma ye ẹ) ati oriṣiriṣi awọn eyiti a ko le darukọ tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o,

"Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ."

JOSHUA O. ADE: CRAIG, *Alabojuto*.


## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kotu, l' Eko.


## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni oriṣiriṣi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.


---


## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ loriṣiriṣi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni Ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.



## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary*.)

A nta oriṣiriṣi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni Popo-nla (*Broad Street*,) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser*.) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo onisowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorişirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'Eko.

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko.

Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

AWON ẸGBẸ OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

## E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranşẹ ọja fun enikẹni to ba tẹ' ibaşe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwon 'si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba tẹ ba awọn oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*,) ati ni ibi-ifi Ọja pamo si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awon Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.